WORKING TO EMPOWER

# AWON AARUN TI A LE KO LATI IBI IBALOPO.

Awon iru aarun wonyi li a le ko lati ibi ibalopo laarin eniyan meji. Awon miran le ran eniyan nigba ti a ba fi ara kan awon eniyan to ni iru arun yi.

Gbogbo eniyan to ba ti n ni ibalopo, yala laarin okunrin ati obinrin tabi awon ona ibalopo miran, li o le ko awon arun yi. Koda awon ti ko ni ibalopo pelu opo eniyan gan le ko iru awon arun yi.

Opo iru awon arun yi lo wa, won fere to marundinlogbon awon arun yi ti a maa n se alabapade. Ninu awon to wopo julo ni arun HIV, atosi, ina abe, ati bebe lo.

O je ohun to dara wipe itoju to peye wa fun opo awon arun wonyi ti a ba tete lo si ile iwosan, arun HIV nikan ni ko gbooogun. Ti a ko ba tete se itoju awon arun yi, o le fa opo isoro fun eniyan. O le fa airomobi fun obinrin, o le fa arun okan ati opolo, o si le pa eniyan. A ni lati ranti wipe, awon arun wonyi le je ki eniyan tete ko arun HIV pelu.

Awon orisirisi kokoro li o maa n fa awon arun wonyi.

Ni awon akoko miran , o maa n soro lati mo eni ti o ti ko awon arun yi. Iru awon eniyan wonyi ko ni ri apeere kankan bi o ti wu ki o ri. Ni awon igba miran, awon apeere arun yi a maa be eniyan wo ni igba kookan bi o tile je wipe arun yi n tesiwaju ninu ara iru eniyan bee.

Ni awon akoko miran, o le to iru arun yi meji tabi jube lo lara eniyan kan soso. Idi niyi ti a ni lati ri awon eleto ilera nigba ti enikeni ba ni ibalopo ni ona ti o lewu, ti o si sese ki iru eni be ti se ibapade iru awon arun yi. O sese ki iru eni bee maa ti bere si ni ri apeere arun arun yi.
Awon to wopo ninu apeere awon arun ti a le ko lati ibi ibalopo ni:

Ki nkan ma jade lati oju ara.

Ki ito maa jo eniyan ni idi.
Ki eniyan ni egbo, tabi ki abe maa hun eniyan.
Ki a maa ri eje li oju ara lehin ibalopo.
Ki abe maa ro eniyan.

O ye ki eniyan tete lo ri awon eleto ilera lehin ti eniyan ba ni ibalopo li ona to li ewu, tabi ti iru eni bee tabi enikeji re ba ni ibalopo pelu awon eniyan miran, tabi ti enikeji iru eni bee ba okan ninu awon apeere ti a ti soro nipa won tele.

Awon apeere wonyi le bere si ni fi ara han lehin ojo meji tabi merinla lehin ti eniyan ti ko arun wonyi. Ni igba miran , o le to osu kan tabi ju be lo. Arun HIV ko ni fun ni ni apeere fun opo odun, o si le to osu meta ki ayewo to le fi arun yi han.

Nipa ibalopo li a le ko awon arun wonyi. Aato okunrin, oje abe obinrin, ati eje li o maa n gbe awon kokoro ti o maa n fa awon arun yi.

Ko di igba ti gbogbo aato okunrin ba jade ki a to le ko awon arun yi, ni iwon igba ti aato die bati jade lara okunrin, arun yi le ran eniyan.
A ni lati mo wipe ni kete ti ara ba ti kan ara, awon aarun wonyi le ran eniyan.

**1. Arun HIV** a maa doju awon olopa ara wa bole patapata, eyi si maa je ki awon aarun pepepe bere si ni ba eniyan ja. Ninu awon arun wonyi ni iko-fere, igbe gbuuru, ati bebe lo.

Arun AIDS li o maa n waye ni igba ti eni ti o ba ni kokoro HIV ninu eje ba bere si ni ri awon apeere ti a ti soro won tele. Awon aarun pepepe wonyi si le se okunfa iku fun iru eni bee.
Kokoro HIV a maa wa ninu eje, aato okunrin, omi oyan, ati oje abe obinrin. Ohun ti o ba le je ki awon ohun wonyi wo inu ara eniyan le je ki kokoro HIv wo inu ara eniyan. Aawo ara wa maa n se aba fun wa, sugbon ti a ba li egbo kankan lara, eyi le je ki kokoro HIV wo inu ara wa pelu.
Nipa ibalopo , tabi nipa gbigba eje ti a ko yewo daadaa, li a fi le tete ko arun HIV. A tun le ko arun HIV ati awon arun miran ti a ba fi enu kan abe elomiran nigba ibalopo.
Obinrin ti o ba li arun HIV le fun omo re ni arun yi ninu oyun, li akoko irobi, tabi lati inu omi oyan.

Arun HIV le ma fun eniyan ni apeere kankan, tabi ki awon apeere ti o fun eniyan ma ja mo nkankan rara. Opo awon ti o ni arun yi ko mo rara wipe awon ti ko arun naa, won si le wa ni alaafia fun nkan bi odun mewa. A ni lati mo wipe awon eniyan bayi si le ko arun yi ran awon ara yoku.
Lehin akoko die, awon apeere kan le maa bere si ni yoju si iru eni bee. Bi o ti wu ki ori, o le to odun die ki arun AIDS to da eniyan wole patapata. Arun AIDS si le pa eniyan laarin osu mefa si odun meji lehin igba ti o ba ti da eniyan wole. Ninu awon apeere ti o le toka

si arun AIDS ni, ara gbigbona ti o ti ju osu kan lo, igbe gbuuru ti o ti ju osu kan lo, awon arun jejere kan, arun opolo, ati bebe lo.
Li opo igba, awon aarun pepepe kan tabi meji a si maa ba iru eni bee ja.
A ko ti ri iwosan fun arun HIV. Awon oogun kan ti wa eyi ti o le ran awon to ni arun yi lowo. Sugbon li opo igba awon oogun wonyi le da eniyan laamu gidi, ti oogun wonyi ko si ni sise lara awon elomiran rara.

A ni lati maa lo roba abo nigba ti a ba ni ibalopo eyiu to le mu ewu dani, a ko si gbudo ya abere lo lati fi gun ara wa.
A ni lati tete se itoju awon arun ibi ibalopo toku nitoriwipe won le tete je ki eniyan ko arun HIV. A ni lati maa se ayewo ara wa dede.
Awon ona wonyi a ran wa lowo lati dena kiko arun HIV.

**2. Arun Chlamydia** je arun to wopo laarin awon okunrin ati obinrin. Arun yi se le je ki eniyan tete ko arun HIV, paapaa ti koba tete se itoju re daadaa. Omo le ko arun yi lati ara iya ni akoko irobi, arun yi sit un le fa otutu aya fun eniyan.
A le ri apeere arun yi lara eniyan lehin ose kan si meta ti eniyan ti ko arun yi.
Opo eniyan si ni arun yi, sugbon won ko mo rara, nitoripe won ko ni apeere kankan lara.

Arun Chlanydia le je ki nkan maa jade lati oju ara eniyan, o le je ki eje maa jade lati oju ara obinrin, o si le je ki abe okunrin wu.
Arun yi le dana obinrin tabi okunrin lati ri omo bi.
Awon oogun oyinbo wa lati se itoju arun yi. A ni lati ri wipoe a lo gigbi awon ogun yi tan ki a ba le mu awon kokoro yi kuro ninu ara wa patapata.

Lilo roba ni igba ibalopo a maa dena kiko arun yi, a si ni lati maa se ayewo ara wa dede.
Atosi je arun to wopo gidi laarin awon okunrin ati obinrin. Kokoro ti o maa n fa arun yi a maa wa ninu aato okunrin ati oje abe obinrin.

**3. Arun atosi** si le tete je ki eniyan ko arun HIV, obinrin si le ko arun yi ran omo re li akoko irobi. Eyi la mu ki oju iru mo fo patapata.

O le to ojo meji si mewa ki arun yi to fi apeere han lara eniyan. Ni opo igba, awon apeere wonyi ko ni fi ara han rara.

Lara awon apeere ti arun atosi le fa ni ki nkan maa jade lati oju ara eniyan, ki ito maa jo eniyan ni idi, tabi ki abe maa ro eniyan.

Arun atosi le fa isoro airomobo lara okunrin ati obinrin,, arun yi si le wo inu eje, eyi ti o le fa arun orikerike ara, ati arun opolo.

Oogun oyinbo wa lati se itoju arun yi.

Lilo roba ni akoko ibalopo le dena kiko arunyi. A si ni lati maa se ayewo ara wa bi o ti ye.

**4. Awon orisi kokoro meji li o maa n fa arun Herpes.** Orisi kan li o maa n fa arun enu, ti orisi keji a maa fa arun ibalopo. Ti eniyan ba ti ko arun yi, o soro ki o to tan lara eniyan patapata. Bi o ti wu ki o ri, itoju wa fun arun yi.
A le dena arun yi nipa lilo roba li akoko ibalopo.

**5. Arun Syphilis** je arun to lagbara gidi. Ipa mata ni arun yi maa n ko ninu ara. Arun yi si le tete ran eniyan ni akoko ipa kini ati ikeji.
Lati ibi ibalopo ni arun yi ti maa n tan kale, sugbon aboyun le ko arun yi ran omo inu re. Arun syphilis le tete je ki eniyan ko arun HIV, o si soro lati se itoju arun yi lara awon to ni arun HIV. Arun yi le se opo ibaje ninu ara , o si le fa iku wa .
Ipa meta ni arun Syphilis le ko ninu ara eniyan:
Ni akoko, egbo kekere kan le jade li oju ara iru eni bee, egbo yi ko ni fa irora rara, a si ma jinna ni kiakia.

Lehin nkan bi osu mefa ni ipa keji arun yi a maa bere. Ni akoko yi awon apeere wonyi li a maa n ri ni ara iru eniyan bee. Ninu won li iba, ara riro, ki irun eniyan maa ja danu,ati ki egbo maa jade si eniyan lara.

O le to nkan bi odun mewa ki ipa keta arun syphilis to bere lara eniyan. Ni akoko yi, arun naa a maa ba opolo ati okan alaisan bee je.

Awon oogun wa lati se itoju arun syphilis. Awon to ni arun HIV pelu arun syphilis ni lati lo awon ogun wonyi fun akoko to pe die ki a to da awon ogun na duro. O se Pataki ki a yago fun ibalopo titi a o fi lo gbogbo awon oogun wonyi tan, a si ni lati se awon ayewo eje ki a le ri daju wipe aarun yi ti tan lara iru eni bee.

Lilo roba ni akoko ibalopo se Pataki lati dena arun syphilis. A si ni lati maa se ayewo dede ki a le ri wipe a ko n arun yi lara.

**6. Awon orisi kokoro kekeke ti o n gbe li abe awo ara eniyan li o maa n fa arun wart .** Iru awon kokoro wonyi kan le se okunfa arun jejere ile omo lara obinrin, tabi jejere ile igbe eniyan. Awon to ni arun HIV ni arun yi maa n yo lenu ju nitoripe awon olopa ara won ko li agbara lati gbogun ti awon kokoro yi bi o ti ye. O soro gidi ki a to le mu kokoro wonyi kuro li ara patapata.
Li akoko ti ara ba kan ara li kokoro a maa tan kale.

Apeere arun yi le to ose die ki o to fi ara han. Arun yi a ma je ki awon ohun kan wu jade lati ara eniyan. Arun yi le je jade li inu oju ara obinrin, bakannna o le je yo lati ara nkan omokunrin eniyan.

O soro lati mu kokoro ti o maa n fa wart kuro lara patapata. Bi o ti wu ki o ri, awon ogun oyinbo wa lati se itoju arun wart. O si se Pataki lati toju gbogbo eniyan ti o ba n ni ibalopo pelu iru eni ti o ba ni arun yi. O se Pataki ki a lo roba ni akoko ibalopo titi a o fi se iwosan na tan.

Lilo roba ni akoko ibalopo je ona ti o se Pataki lati dena kiko arun wart yi.

**Translated into Yoruba Language by;**
**Dr. ADEOTI, Abolaji.**
**Pretoria, South Africa.**
**15th, January 2008.**